**WoW ORIN YORUBA - Ọjọ́ Kínní, Oṣù Kẹfà, Ọdún 2020**
**<u>Ìwé Orin Ìjọ Elétò</u>**

**<u>Orin 1</u>** – St Leonard (Henry Smart)

1: Mbá lè ní ẹgbẹ̀rún ahọ́n
Ki nyin Olùgbàlà
Ògo Ọlọ́run Ọba mi
Ìṣẹ́gun ore Rẹ̀.

2: Baba mi àt' Ọlọ́run mi
Fún mi ní ìrànwọ́ Rẹ
Kí nlè rò ká gbogbo ayé
Ọlá Orúkọ Rẹ.

3: Jésù t'Ó s'ẹrù wa d'ayọ̀
T'Ó mú 'bànújẹ́ tán
Orin ni l'ètí ẹlẹ́ṣẹ̀
Ìyè àti 'lera.

4: Ó sọ̀rọ̀, òkú gbóhùn Rẹ̀,
Ó gba ẹ̀mí titun
Onírò-bínújẹ́ y' ayọ̀,
Òtòṣì sì gbàgbọ́.

5: Ó ṣẹ́gun agbára ẹ̀ṣẹ̀,
Ó dá ara túbú
Ẹ̀jẹ̀ Rẹ̀ lè w' ẹlẹ́rìí mọ́
Y' Ó wẹ̀ mí mọ́ pẹ̀lú.

6: Wò a k' ẹ̀ṣẹ̀ yín lé Jésù
Ọ̀d'ágùntàn t' a pa
Ẹnití a ti fi rúbọ
Fún gbogbo ènìyàn.

*Charles Wesley, 1707-1788*

**Orin 2** – Fulda (Gardiner's Sacred Melodies)

1: Gbogbo ẹ̀yin tí ńgbé ayé,
Ẹ f' ayọ̀ kọrin s' Olúwa;
F' ìbẹ̀rù sĩn, ẹ yĩn lógo;
Ẹ f' ayọ̀ wá síwájú Rẹ̀.

2: Olúwa, Òn li Ọlọ́run;
Ó dá wa láìsí 'rànwọ́ wa;
Tirẹ̀ l' awã ṣe, Ó mbọ́ wa;
Ó ńtọ́jú wa b' ágùntàn Rẹ.

3: Ẹ f' iyìn wọ ilé Rẹ̀ wá ;
Ẹ f' ayọ̀ súnm' ágbàlá Rẹ̀;
Ẹ yĩn, ẹ bùkún õkọ Rẹ̀,
N'torí bẹ́' l' ó yẹ k' á mã ṣe.

4: N'torí rere l' Ọlọ́run wa,
Ànú Rẹ̀ wà bákanáà láí;
Ọ̀tọ́ Rẹ̀ kò fi 'gbà kan yẹ,
Ó dúró lát' iran dé 'ran.

*William Kethe, d. 1593*

**Orin 4** – Hanover (W. Croft)

1: Ẹ wólẹ̀ f' Ọba, Ológo jùlọ,
Ẹ kọrin ipá àti ìfẹ́ Rẹ̀;
Alãbò wa ni, at' Ẹni Ìgbanì,
Ó ńgbé inú ògo ẹlẹ́rù n' íyìn.

2: Ẹ sọ t' ipá Rẹ, ẹ sọ t' õre Rẹ;
'Mọlẹ l' aṣọ Rẹ, kọ́bí Rẹ̀ ọrun,
Bi ãrá ti nsán ni kẹkẹ 'binu Rẹ;
Ipa ọna Rẹ li a kò si lè mọ.

3: Aiye yi pẹlu ẹkún rẹ gbogbo,

Olodumare! Iwọ l' O da wọn,
O f' idi rẹ mulẹ, o duro ṣinṣin,
O sì fi òkun yi gbogbo ilẹ ká.

4: Itọju Rẹ wà lara gbogbo wọn,
Ninu afẹfẹ, ninu imọle;
Itọju Rẹ wà ninu odo ti nṣàn,
O si wà ninu ìri ati òjo.

5: Awa erupẹ, aw' alailera,
'Wọ l' a gbẹkẹle, O ki o dà ni;
Anu Rẹ ni 'ronú, o duro lailai,
Ẹlẹda, Alãbo, Olugbala wa.

6: 'Wọ Alagbara, Onifẹ julọ,
B' awọn angẹli ti nyìn Ọ loke.
Bẹ l' awa ẹda Rẹ, niwọn t' ã le 'ṣe,
A o ma juba Rẹ, a o ma yin Ọ. Amin.

*Robert Grant, 1785-1838*

**Orin 19** – Millenium (unknown)
1: Mo f' iyin ailopin
Fun Ọlọrun Baba;
Fun õre aiye mi,
At' ireti t' ọrun.
O ran Ọmọ Rẹ ayanfẹ
Lati kú fun ẹṣẹ aiye.

2: Mo f' iyin ailopin
Fun Ọlọrun Ọmọ;
T' o f' ẹjẹ Rẹ rà wa
Kuro ninu egbe;
Nisisiyi O wà l' Ọba
O nrí èso irora Rẹ.

3: Mo f' iyin ailopin

Fun Ọlọrun Ẹmi;
Ẹni f' agbara Rẹ,
Sọ ẹlẹṣẹ d' ãye.
O pari iṣẹ igbala,
O si fi ayọ̀ kun ọkàn.

4: Mo f' ọla ailopin
Fun Olodumare,
'Wọ Ologo-Mẹta
Ṣugbọn Ọkanṣoṣo;
B' o ti ju imọ wa lọ ni,
A o mã f' igbagbọ yin Ọ.

*Isaac Watts, 1674-1748*

**Orin 9** – Regent Square (Henry Smart)

1: Ọkàn mi, yin Ọba ọrun,
M' ọrẹ rẹ wá s' ọdọ Rẹ;
'Wọ t' a wòsan t'a dariji,
Tal' ò ba ha yin bi Rẹ?
Yin Oluwa, Yin Oluwa,
Yin Ọba ainipẹkun.

2: Yĩn fun anu Rẹ si awọn
Baba wa n'nu 'pọnju wọn;
Yin I, ọkannã ni titi,
O lọra lati binu;
Yin Oluwa, Yin Oluwa,
Ologo n'nu otitọ.

3: Bi baba li O ntọju wa
O sì mọ ailera wa;
Jẹjẹ l' O ngbe wa l' apa Rẹ,
O ngbà wa lọwọ ọta;
Yin Oluwa, Yin Oluwa,
Ãnu Rẹ yi aiye ká.

4: Ẹnyin angẹl', ẹ jubà Rẹ;
Ẹnyin nrĩ lojukõju;
Òrùn, oṣupa, ẹ wolẹ,
Ati gbogbo agbaiye,
Ẹ ba wa yin, Ẹ ba wa yin
Ọlọrun Olor'-ọfẹ.

*Henry Francis Lyte, 1793-1847*